# Adébáyọ̀ Fálétí Dará Ilẹ̀

Adedotun Ogundeji (Àtàrí Àjààkú)
Department of Lingusitics and African Languages
University of Ibadan
Nigeria
dotogundeji@gmail.com

Àkàndé ìjí, Ọlọ́yẹ́moyin òòò
Ojú kan  ní í bíni
Igba ní í woni dàgbà
Ìwọ nìkàn, Elétùú, Ọdẹ orófó
Mọlọ́yẹ́moyin, Ọdẹ àdàbà
O jọgọ́rùn-ún baba fúnrúu wa
Ìwọ òjìnmí onímọ̀ àṣà àtèdè
Ọ̀kàn ni mí lára òròmọdìẹ
Tó ó kọ́ ní Fáfitì ẹlẹ́rankoòlúùbàdàn
Ọ̀kàn ni mi lára ọ̀jẹ̀ wẹ́wẹ́ olùwadìí
Tó o bùn nímọ̀ mu
Láti inú òdù àmù ikùn
Baba onínúure, tó jàpapọ̀ baba ẹlòmíìn
Baba mi, Pa-nílé-o-tó-roko
Kò sí ká lọ ká bọ̀ lọ́rọ̀ tirẹ
Ìwọ lo pa, pa, pa
Tó o pèyí tí í pa baálé rẹ ládìẹ jẹ o tó roko
Kánmọ́-ń-kíá lò ó dáni lóhùn
 Ní gbogbo ọjọ́ tá a báwadìí wọ́dọ̀ rẹ
Àkàndé,  aráàjíléje
Moṣọbalájé, Mọlọ́yẹ́moyin ò
Ìwọ  lo ò jẹ́ n rá sígbó elégbèje ọgbọ́n
Ajíbádé, Elétùú, Àjànàkú gbédè-gbẹ́yọ̀
Ìwọ màmà ló ò jẹ́ n nù síjù irúnmọlẹ̀ ìmọ̀

Níbi mo gbé ń wáhun tí ò nù kiri
Bí Ìrìnkè àtÀkàrà
Afàìmọni kónimọ́ra
Òbọ̀mọdé dọ́rẹ̀ẹ́ bí ojúgbà ẹ̀
Àwọn ẹnì tí ò gbọ́n, àwọn ẹnì tí ò mọ̀ràn
Wọn lọ́kẹ̀ẹ́rẹ́ gorí ìrókò ojú ọdẹ dá
Wọn ò mọ̀ pé bíi ti baba mi Àkàndé ìjí kọ́
Bó o ti jóní-tọgi-pin ìlasà,
Lo jójìnmí onímọ̀ ìjìnlẹ̀
Ìwọ làjànàkú akewì-kéwì
Àràbà eléré ìtàgé òun fídìoò
Ògúnná gbòǹgbò oníròyìn
Àgbà ọ̀jẹ̀ alákòósoo
Mo ṣe bí bọ́dẹ bá kúuù
Wọ́n lọ́dẹ è é sunkúnunùn
Àwọn ọdẹ è é gbààwẹ̀ẹ
Èrèmọ̀jé elérèéè
Ni án lọdẹ́ fi í ṣoròò lẹ́yìn ọdẹẹẹ
Mọ̀jé eléréèé....
Elérèé ooo
Baba èrèmòjielè
Ajíbádé, aráàjílèje
Pa-nílé-o-tó-róko
Àkàndé Mọlọ́yẹ́moyin
Òjìnmí onímọ̀ àṣà àtèdè
Ìrèmọ̀jéè mi rèé oooo.
Ká tóó tún rérin ó digbó rérérééè
Ká tóó tún rẹ́fọ̀n, ó dọdàn jìnnàjìnnà
Ká tóó tún rẹ́ni tí ó ṣe bí Àkàndé ìjí
Ajíbádé, Elétùú, ọdẹ àdàbà
Moṣọbalájé Elétùú, ọdẹ òrófó
Ó dọ̀run alákejiiii
Orin:
*Gẹ̀ẹ̀gẹ̀ la ó gbe e;*
*Gẹ̀ẹ̀gẹ̀ la ó gbe e*
*Òkú ọlọ́ọ́mọ;*
*Gẹ̀ẹ̀gẹ̀ la ó gbe e..*

